


BRAIN BUILDERS
YOUTH DEVELOPMENT
INITIATIVE

# Irinṣẹ´Ìjábọ̀ fún ará Ìlú

Sponsored by: LEAP AFRICA NIGERIA YOUTH FUTURES FUND

BRAIN BUILDERS
YOUTH DEVELOPMENT
INITIATIVE

# Irinṣẹ́ Ìjábọ̀ fún ará Ìlú

© Copyright, Brain Builders Youth Development Initiative (BBYDI)

# Àtẹ Àkóónú


| | |
|---|---|
| Ọ̀rọ̀ Àsọsáájú | 1 |
| Níní Òye nípa Àwọn Ẹ̀tọ́ Wa Àti Ojúṣe wá gẹ́gẹ́ bíi ará ìlú | 3 |
| Àwọn irinṣẹ́ Fún ìbáṣepọ̀ Ará Ilú Lẹ́yìn Ètò Ìdìbò Àti Mímú Àwọn Ìjọba Jábọ̀ Ojúṣe Wọn | 4 |
| Ibáṣepọ̀ Àwọn Ará Ilú Àti Mímú Ìjọba Jábọ̀ Lórí Ojúṣe Wọn Nípasẹ̀ Ominira Alayé Iṣẹ́ Òfin (FOS) | 5 |
| Ibáṣepọ̀ Àwọn Ará Ilú Àti Mímú Ìjọba Jábọ̀ Lórí Ojúṣe Wọn Nípasẹ̀ Ìpàdé Ìgbọ́ràn Gbogbogbò | 9 |
| Ibáṣepọ̀ Àwọn Ará Ilú Àti Mímú Ìjọba Jábọ̀ Lórí Ojúṣe Wọn Nípasẹ̀ Ìpàdé àwọn àgbègbè ní gbòngàn ìlú | 13 |
| Ibáṣepọ̀ Àwọn Ará Ilú Àti Mímú Ìjọba Jábọ̀ Lórí Ojúṣe Wọn Nípasẹ̀ Ìwé ẹ̀bẹ̀ | 16 |
| Ibáṣepọ̀ Àwọn Ará Ilú Àti Mímú Ìjọba Jábọ̀ Lórí Ojúṣe Wọn Nípasẹ̀ Ilé ẹjọ́ | 21 |
| Ibáṣepọ̀ Àwọn Ará Ilú Àti Mímú Ìjọba Jábọ̀ Lórí Ojúṣe Wọn Nípasẹ̀ Ìwé àdéhùn ọmọ ìlú | 23 |
| Ìkádìí | 26 |
| Àwọn Ohun Èlò Síwájú Sí i | 27 |

# Ọ̀rọ̀ Àsọsáájú

Lẹ́yin ètò ìdìbò tí ó waýé láìpẹ́ yìí ní orílẹ̀ èdè Nàìjíríà, èyí tí ó waýé ní ọjọ́ karùndínlọ́gbọ̀n, oṣù Èrèlé, ọdún 2023, àti ọjọ́ kejìdínlógún, oṣù Ẹrẹ́nà, ọdún 2023, ààrẹ tí wọ́n dìbò yàn, igbákejì ààrẹ tí wọ́n dìbò yàn àti àwọn mìíràn tí wọ́n dìbò yàn ti gorí àléfà. Wọ́n búra fún Ààrẹ àti igbákejì Ààrẹ ní ọjọ́ kọkàndínlọ́gbọ̀n, oṣù Èbìbí, ọdún 2023, nígbà tí wọn yóò búra fún àwọn ọmọ ẹ̀gbẹ́ ilé asòfin ní ọjọ́ kọkànlá, oṣù Okúdù, ọdún 2023.

Ààrẹ tí a yàn, igbákejì ààrẹ, àwọn Gómìnà, àti àwọn igbákejì Gómìnà ni a nírètí wí pé wọ́n gbọdọ̀ sin ìlú fún ọdún mẹ́rin, bẹ̀rẹ̀ láti ọjọ́ tí wọ́n ti búra fún wọn sínú ipò náà. Síbẹ̀síbẹ̀, wọ́n lè rọ́pò wọn tí wọ́n bá yọ wọ́n kúrò, kọ̀wé fipò sílẹ̀ tàbí wọ́n ṣaláìsí. Igbákejì ààrẹ tàbí igbákejì Gómìnà ni yóò gun orí àléẹ́fà tí iru ́nǹkan bẹ́ẹ̀ bá ṣẹlẹ̀.

Ní ti àwọn asòfin tí wọ́n yàn, a lérò wí pé wọ́n gbọdọ̀ sin ìlú fún ọdún mẹ́rin tí wọ́n bá búra fún wọn ní ìbẹ̀rẹ̀ ìgbìmọ̀ asòfin. Tí wọn bá yan asòfin nípa ìdìbò pàtàkì (èyí tí a mọ̀ sí ìdìbò tí ó kọjá), àsìkò tí ó yẹ kí ́wọ́n lò yóò wá sí òpin pẹ̀lú ìgbìmọ̀ asòfin tí ó ń lọ lọ́wọ́. Àwọn ìdí kan wà nibi tí asòfin lè má le parí àsìkò rẹ̀, bí i tí ọlọ́jọ́ bá dé, tàbí di pípè padà pẹ̀lú ìdá tó pọ̀ jù tó dìbò ní ẹkùn àgbègbè wọn tàbí wọ́n jẹ̀bi ẹ̀sùn tàbí ìwà ọ̀daràn nílé ẹjọ́ .

Tí ààyè bá ṣí sílẹ̀, àjọ tí ó ń rí sí ètò ìdìbò (INEC) ni ó lẹ́tọ̀ọ́ láti sètò ètò ìdìbò kòmẹsẹ̀ ó yọ láàrin àádọ́rùn-ún ọjọ́ láti dí ààyè tó sófo.

**Ètò ìdìbò ṣe pàtàkì ní awùjọ tiwantiwa, bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé kò sí ìdánilójú ipa ará ìlú lórí ṣíṣètò àmúlò tàbí ìṣàkóso ìjọba tí ó mọ ojúṣe. Àmọ́ ṣáá, wọ́n gba àwọn ará ìlú láàyè láti yan adarí wọn àti láti kópa tó jọjú nínú ṣíṣe ìpinnu. Ó ṣe pàtàkì láti rí ètò ìdìbò gẹ́gẹ́ bí i àǹfààní láti ró àwọn ará ìlú lágbára, ṣe àgbéga ìkópa onílọsíwájú, kí ́ó sì mú ìdàgbàsókè ẹ̀mí ìfọkànsí láàrin àwọn tí wọ́n yàn sí ipò.**

Ní títẹ̀síwájú, ó ṣe pàtàkì láti rí i dajú wí pé àwọn ará ìlú ń kopa, kí wọ́n sì rí i wí pé àwọn aṣojú wọn tí wọ́n yàn ń jíyìn iṣẹ́ ́wọn. Nípa kíkópa tó jọjú nínú ètò ọ̀ṣèlú, àwọn ara ̂ìlú le ṣe ìrànlọ́wọ́ nípa àtúntò àwọn ètò àmúlò ijọba àti rí i wí pé wọ́n ń lo àwọn ohun ìgbẹ́kẹ̀lé ti ìpínlẹ̀ wọn lọ́nà tó tọ́.



# Níní Òye nípa Àwọn Ẹ̀tọ́ Wa Àti Ojúṣe wá gẹ́gẹ́´bíi ara´ìlu´

Àwọn ará ìlú ní ẹ̀tọ́ àti ojúṣe, lára rẹ̀ ni ẹ̀tọ́ láti kópa nínú ìpinnu tó ní ipa lórí àgbègbè wọn. Kíkópa kì í ṣe pàtàkì fún ìjọba tiwantiwa nìkan, ṣùgbọ́n ó tún mú àyípadà rere bá ìlú àti ró àwọn ará ìlú lágbára. Kíkópa àwọn ará ìlú ṣe kókó lákòókò àti láàrin ètò ìdìbò, ó sì le ṣe é ṣe nípasẹ̀`onírúurú ìkànnì bí i ileéṣẹ́ orílẹ̀ èdè, àwọn àgbéká mìíràn àti orí ẹ̀rọ ayélujára láti rí i wí pé ìṣirò/ìjábọ̀ dájú, àwọn ará ìlú gbọdọ̀ kópa nínú ètò òṣèlú. Wọ́n le bèèrè fún adarí tó kúnjú òsùnwọ̀n kí wọ́n sì rí i wí pé àwọn adarí tí wọ́n dìbò yàn mú ìlérí´wọn ṣẹ. Fún ìjọba tiwantiwa láti ṣiṣẹ́ dáradára, àwọn ará ìlú tí ó ń kópa níbi ètò òṣèlú gbọdọ̀`lọ́wọ́ sí gbogbo ẹ̀ka ṣíṣe ìpinnu òṣèlú, pẹ̀lú gbogbo ìlànà ètò ìdìbò, ilànà àlàáfíà àti ìlànà kíkọ́ òfin.

Àwọn ará ìlú ní ẹ̀tọ́ àti ojúṣe, lára rẹ̀ ni ẹ̀tọ́ láti kópa nínú ìpinnu tó ní ipa lórí àgbègbè wọn. Kíkópa kì í ṣe pàtàkì fún ìjọba tiwantiwa nìkan, ṣùgbọ́n ó tún mú àyípadà rere bá ìlú àti ró àwọn ará ìlú lágbára. Kíkópa àwọn ará ìlú ṣe kókó lákòókò àti láàrin ètò ìdìbò, ó sì le ṣe é ṣe nípasẹ̀`onírúurú ìkànnì bí i ileéṣẹ́ orílẹ̀ èdè, àwọn àgbéká mìíràn àti orí ẹ̀rọ ayélujára láti rí i wí pé ìṣirò/ìjábọ̀ dájú, àwọn ará ìlú gbọdọ̀ kópa nínú ètò òṣèlú. Wọ́n le bèèrè fún adarí tó kúnjú òsùnwọ̀n kí wọ́n sì rí i wí pé àwọn adarí tí wọ́n dìbò yàn mú ìlérí´wọn ṣẹ. Fún ìjọba tiwantiwa láti ṣiṣẹ́ dáradára, àwọn ará ìlú tí ó ń kópa níbi ètò òṣèlú gbọdọ̀`lọ́wọ́ sí gbogbo ẹ̀ka ṣíṣe ìpinnu òṣèlú, pẹ̀lú gbogbo ìlànà ètò ìdìbò, ilànà àlàáfíà àti ìlànà kíkọ́ òfin.






# Àwọn Irinṣẹ́ Fún Ibáṣepọ̀ Ará Ilú Lẹyin Ètò Ìdìbò Àti Mímú Àwọn Ìjọba Jábọ´Ojúṣe Wọn



**Òmìnira àlàyé iṣẹ́ òfin**



**Ìwé adéhùn àwọn ọmọ ìlú**



**Ìgbọ́ràn gbogbogbò**



**Ilé ẹjọ́**



**Ìwé ẹbẹ̀ lórí ẹ̀rọ ayélujára**



**Ìpàdé àwọn agbègbè**



# Ibáṣepọ̀ Àwọn Ará Ilú Àti Mímú Ìjọba Jábọ´Lórí Ojúṣe Wọn Nípasẹ̀ Ominira Alayé Iṣẹ́ Òfin (FOS)

Òmìnira àlàyé iṣẹ́ òfin ti orílẹ̀`èdè Nàìjíríà di fífọwọ́sí gẹ́gẹ́ bí i òfin ní ọjọ´ kejìdínlọ́gbọ̀n, oṣù Èbìbí, ọdún 2011, nípasẹ̀`ààrẹ tẹ́lẹ̀ rí, Ààrẹ Goodluck Ebele Jonathan gẹ́gẹ́ bí òfin tí ó ṣe ìdánilójú fún gbogbo ènìyàn láti ní àǹfààní sí àwọn ìgbàsílẹ̀`àti àlàyé tí ó wà ní àgbègbè gbogbo ènìyàn. Abala kejìlélọ́gbọ̀n náà tún wà láti dáàbò bo àwọn ìgbàsílẹ̀`gbogbo ènìyàn àti àlàyé fún ìwúlò gbogbo ènìyàn àti dáàbò bo àwọn oṣìṣẹ́ gbangba láti jìyà tàbí ṣẹjọ́ fún fífi àwọn àlàyé kan sí ìta laì gba àṣẹ. Nínú àsọṣáájú rẹ̀, òfin naâ sọ ní sókí – òfin kan láti ṣe àwọn ìgbàsílẹ̀`àti àwọn àlàyé láti wà ní àrọ́wọ́tó fún gbogbo ènìyàn ní àǹfààní sí àwọn ìgbàsílẹ̀`àwọn ènìyàn àti àlàyé, dáàbò bò àwọn ìgbàsílẹ̀`àwọn ènìyàn àti àlàyé, débi wí pé pẹ̀lú ìwúlò ti gbogbo ènìyàn àti ìkọ̀kọ̀ ti ara ẹni, dáàbò bo àwọn oṣìṣẹ́ ìjọba láti àwọn ara àbájáde búburú fún sísọ àwọn àlàyé kan láì gba àṣẹ àti ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ètò fún ìmúṣẹ àti àṣeyọrí àwọn ìdí yẹn; fún ọ̀rọ̀ tó jẹ mọ́. Láti inú àlàyé tó wà lókè yìí, ó hàn gbangba wí pé òfin (FOI) sọ di òfò ìpèsè àwọn òfin bí i òfin àṣírí ìsiṣẹ́ àti òfin ọ̀daràn tí ó ń ṣe òfin lòdì sí sísọ ní gbangba àwọn alàyé ìjọba láì gba ade. Kódà, gẹ́gẹ́ bí orin àpapọ̀ olómìnira orílẹ̀`èdè Nàìjíríà, àwọn ìpèsè òfin oṁìnira àlàyé rékọjá ti òfin èyíkéyìí tó bá wà nípa ìpamọ´àti sísọ àwọn àlàyé ìjọba ní orílẹ̀ èdè Nàìjíríà.

# Ìtalóbobó Lorí́ Ọnà Láti Lo Òfin Ominira Alayé (FOI)[1]

## Ṣe ìwádìí rẹ

Ní àkọ́kọ́, àṣeyọrí òfin omìnira àlàyé ní í ṣe pẹ̀lú níní ìdojúkọ, ìwádìí daradára, àti tààrà. Ó yẹ kí ó lò ó nìkan láti beèrè àwọn ìwé àṣẹ tí kò sí ní gbangba ṣaájú ki´o tó ṣe ìforúkọ sílẹ̀`fún ìbéèrè ìwé òfin omìnira àlàyé, ó yẹ kí o ṣe ìwádìí ìwé òfin omìnira àlàyé, ó yẹ kí o ṣe ìwádìí láti pinnu iru´ ìwé tí o ń wá, irú àwọn àjọ wo ni ó ṣe é ṣe láti ní àwọn ìwé àṣẹ naâ, àti irú àwọn ìgbàsílẹ̀`ìjọba ni ó ti wà ní ìta gbangba tẹlẹ̀. Nígbà tí o bá ti pinnu wí pé àwọn àlàyé tí o nílò kò sí ní gbangba, ó yẹ ki´o ṣe ìdánimọ̀`àwọn ìwé àṣẹ kan pàtó, àwọn oríṣìí ìwé àṣẹ tàbí àwọn àkọlé ti àwọn ìgbàsílẹ̀`tí ó fẹ́ wá. Gbogbo àwọn ẹ̀ka aláṣẹ àti iléeṣẹ́ ni ó wà lábẹ́ òfin FOI. Ilé ìgbìmọ̀ asòfin ti orílẹ̀`èdè àti àwọn kóòtù kò ní àbò pẹlú òfin FOI, èyí tí ó túmọ̀`sí o kò le fi ibéèrè FOI ránṣẹ́ sí kóòtù tàbí ilé ìgbìmọ̀ asòfin ti orílẹ̀`èdè. Fi lẹ́tà rẹ sọrí sí olórí ilé-iṣẹ́ ẹ̀ka tí ò ń kọ̀wé sí.

## Kọ lẹ́tà FOI rẹ

Ìbéèrè fún gbígba fọ́ọ̀mù fún òfin FOI alámọ̀dájú ní ìpele yìí. Lẹ́yìn tí o ti ṣe ìwádìí lorí́ irú àlàyé láti bèèrè lọ́dọ̀ àwọn àjọ, o ti ṣetán láti kọ ìbéèrè òfin FOI. Fi lẹ̀tà rẹ ránṣẹ́, yan àjọ tí ó tọ́ nípa wíwá àwọn ilé-iṣẹ́ ìjọba tí ó wà lábẹ́ FOIA, kí o sì ṣe ibéèrè kan pàtó tí ó sì ní afojúsùn. Gbogbo àwọn àjọ ni ó ń gba ìwé méèlì àfiránṣẹ́. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn àjọ yìí tún ń gba àwọn ìbéèrè tí a fi ránṣẹ́ nípa faxi tàbí méèlì. Díẹ̀ nínú àwọn àjọ yìí ni àwọn fọ̀ọ̀mù tí o lè fi ránṣẹ́ lórí ayélujára.

## Fi lẹ́tà ibéèrè FOI rẹ ránṣẹ́

Fi ìbéèrè rẹ ránṣẹ́ sí àwọn ilé-iṣẹ́ ìjọba tí ó wà lábẹ́ òfin FOI (òfin FOI ní í ṣe sí ile´-iṣẹ́ ìjọba àti ti ìjọba àpapọ̀), kí o sì ní ibéèrè kan ní pàtó tí o ní àfojúsùn. Gbogbo àwọn àjọ ni ó ń gba ibéèrè nípa ìfiwé ránṣẹ́. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn àjọ tún ń gba àwọn ìbéèrè tí a fi ránṣẹ́ nípasẹ̀ faxi tàbí ímeèlì. Díẹ̀` nínú àwọn àjọ náà ní àwọn fọ́ọ̀mù tí a lè fi ránṣẹ́ lórí ẹ̀rọ ayélujára.

[1] https://ymonitor.org/request-guide/

## Tọpa lẹ́tà ibéèrè FOI rẹ

Ní kété tí o bá ti kọ àwọn ìbéèrè rẹ, ó ṣe pàtàkì láti tọ́jú abala àlàyé pàtàkì bí i ọjọ́tí o fi ránṣẹ́, àjọ tàbí àwọn àtòpọ̀, kókó ọ̀rọ̀, nọ́ḿbà tí o le fi tọpa àjọ náà, déètì àti èyíkéyìí àtẹ̀lé ìfọ̀rọ̀ránṣẹ́ àjọ, pẹ̀lú fóònù àti émèèlì oní ìfọ̀rọ̀ránṣẹ́. Àlàyé yìí le jẹ́pàtàkì fún àwọn ìbéèrè láti mójútó àwọn ìbéèrè àfiránṣẹ́, àwọn ẹ̀bẹ̀, àti ẹjọ́ àti ìrànlọ́wọ́ láti yàgò fún fífi ẹ̀dà ìbéèrè ránṣẹ́.

Lẹ́yìn tí o fi ẹ̀dà ìbéèrè rẹ ránṣẹ́, eré ìdádúró bẹ̀rẹ̀. Lábẹ́ òfin, àwọn àjọ ní láti fi ìpinnu ìgbẹ̀yìn ránṣẹ́ láàrin àwọn ọjọ́ ìsòwò meje (7), ṣùgbọ́n ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọ́fíìsì òfin FOI ni ó ní ogunlọ́gọ̀ àwọn ìbéèrè tí wọn kò tí ì dahùn.

## Ìdáhùn sí àwọn lẹ́tà ibéèrè FOI rẹ

Ìwọ yóò gba èsì lẹ́tà tí ó tọ́ka wí pé wọ́n gba ìbéèrè rẹ tàbí èyí tó ń ṣe àfihàn ohun tí ó lè dènà tàbí ṣe ìdádúró ibéèrè rẹ, tàbí àwọn ìwé àṣẹ le di fífi kalẹ̀lẹ́kùn rẹ́rẹ́ tàbí ní apá kọ̀ọ̀kan (ṣe àtúnṣe). Wọ́n tún le kọ̀ láti jẹ́rìí sí tàbí kọ̀wí pé àwọn ìwé naâ wà tàbí kọ ìbéèrè fún ìdí ìlànà. Tí o bá di kíkọ̀, o lè pinnu láti rawọ́ ẹ̀bẹ̀ àti fífiránṣẹ́ sí àjọ naâ. Tí ìpinnu ẹ̀bẹ̀rẹ kò bá tẹ́ọ lọ́rùn, o ní ẹ̀tọ́ láti pè ṣẹjọ́fún ìtuśílẹ̀àwọn ìwé àṣẹ ní kóòtù ìjọba àpapọ̀.

## Lo òfin FOI lọ́nà tó tọ́

Láti lo alaỳe ́yìí tí o fi ránṣẹ́, jọ̀wọ́ ṣe bẹ́ẹ̀ lọ́nà tó tọ́. Bèèrè fún ìgbani-laáỳe ̀tí o bá fẹ́ṣe ẹ̀dà ìwé tí wọ́n fi ránṣẹ́sí ọ (tàbí èyí tí ó kéré jù, dárúkọ orísun). Bí ́ó tilẹ̀jẹ́wí pé wọ́n ti fi ìwé àṣẹ naâ ránṣẹ́, àṣẹ lórí ìwé naâ yóò sì jẹ́ti àwọn aláṣẹ tí ó nií tàbí ti ẹnikẹ́ni tí ó fún wọn.

## Àpẹẹrẹ lẹ́tà ibéèrè fún ominira ìwé ase[2]

Orukọ rẹ

Àdírẹ́sì rẹ

Nọ́mbà tẹlifóònù rẹ

Àdírẹ́sì Ímeèlì rẹ

Deéti

Oṡìṣẹ́ oṁiṅira alaỳe

*(O tún lè pinnu láti darí lẹ́tà naâ sí olórí ile-iṣẹ́naâ, èyun: Akọ̀we àgbà, niḃi tí o bá ti jẹ́ ti àjọ; olùdarí – gbogbogbò, niḃi tí ileéṣẹ́, tàbí alakòòso olùdarí, niḃi tí ileéṣẹ́ gbogbogbò).*

Orukọ ileéṣẹ́naâ

Àdírẹ́sì ileéṣẹ́ náà

Oṡìṣẹ́ olómìnira alàyé mi tòótọ́,

**Ìbéèrè fún àlàyé/àwọn ìgbàsílẹ̀/àwọn ìwé àṣẹ labẹ́ òfin oṁìnira àlàye**

Ní ìbámu pẹlú òfin oṁìnira àlàyé ti ọdún 2011, mo bèèrè fún ẹ̀dà àwọn ìwé àṣẹ wọṅyìí:

1. Ẹ̀dà ìwé ìpàdé ti ìgbìmọ̀ ètò rírà ti ileéṣẹ́ tí ó ń rí sí ọ̀rọ̀ abẹ́lé, èyí tí ó wáyé ní ọjọ́ kejìdínlọ́gbọ̀n, oṣù Èbìbí, ọdún 2011, nibi tí ìpinnu ti wáyé láti ra ẹ̀rọ kọ̀ṁpútà alágbèéká ọ̀tà-lénígba ó dín mẹ́wàá (250) fún àwọn òsìṣẹ́ àgbà ti iléeṣẹ́ náà.

2. Àwọn ẹ̀dà ti gbogbo lẹ́tà, pẹlú ímeelì, láàrin àwọn aṣojú ti ileéṣẹ́ àlàyé àti iléeṣẹ́ tí a mọ̀ sí Blue Skies International, láti ọjọ́ kìn-ín-ní oṣù Ṣẹ̀ẹ́rẹ́, ọdún 2011 àti ọgbọ̀n ọjọ́, oṣù Òkudù, ọdún 2011, tí ó yọrí sí fífọwọ́sí ìwé adéhùn ti òye ní ọjọ́ kìn-ín-ní, oṣù Agẹmọ, ọdún 2011.

3. Àtò gbogbo ìwé fún iyọ̀nda ilé kíkọ́ èyí tí a fún ni láti ọwọ́ iléeṣẹ́ ètò ọ̀rọ̀ ìlú láàrin ọjọ́ kọkàndínlọ́gbọ̀n, ọdún 2007 àti ọjọ́ kejìdínlọ́gbọ̀n, ọdún 2011. Àtò naâ gbọdọ̀ ṣe àfihàn orúkọ olùbéèrè, ọjọ́ tí ó fi ìwé ibéèrè ránṣẹ́, ọjọ́ tí wọ́n fọwọ́sí ìwé ibéèrè, irú ilé tí wọ́n fọwọ́sí àti iye owó tí wọ́n san àti ìdíyelé nípasẹ̀ olùbéèrè kọ̀ọ̀kan.

Èmi yóò dupẹ́ bí ẹ bá lè fún mi ní àwọn ẹ̀dà àwọn ìwé àṣẹ yìí.

Tí ẹ bá nílò alàyé èyíkéyìí nipa ìbéèrè yìí, jọ̀wọ́ má ṣiyèméjì láti kàn sími yálà nípasẹ̀ fóònù (nọ́mbà fóònù rẹ) tàbí nípasẹ̀ ímeèlì (àdírẹ́sì ímeèlì rẹ).

Mo ní ìrètí láti gba àwọn ìwé àṣẹ yìí ní kiákíá, ní èyíkéyìí iṣẹ̀lẹ̀, láàrin ọjọ́ méje tí ẹ gba ohun ìbéèrè yìí bí ó ṣe nílò gẹ́gẹ́ bí i òfin oṁìnira àlàyé ti ọdún 2011.

Èmi ni tiyín ní tòótọ́,

Ìbuwọlùwé

Orukọ rẹ

2 https://mediarightsagenda.org/sample-freedom-of-information-request-letter/

# Ibáṣẹ́pọ̀ Àwọn Ará Ilú Àti Mímú Àwọn Ìjọba Jábọ̀ Lórí Ojúṣe Wọn Nípaṣẹ  Ìpàdé Ìgbọ́ràn Gbogbogbò

Ìpàdé ìgbọ́ràn gbogbo ènìyàn jẹ́ gbàgede ibi tí àwọn asòfin, àwọn ara´ìlú, àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn, àti àwọn òsìṣẹ́ ìjọba láti jíròrò, fọ̀rọ̀-jomi-toro-ọ̀rọ̀ àti iṣẹ́ ìjíròrò lórí òfin tí a dábàá ní ilé ìgbìmọ̀ asòfin. Ó pèsè aàyè ìgbéwọlé èròǹgbà gbogbo ènìyàn lórí ètò òfin tàbí òfin tí a dábàá èyí tí ó kan ọ̀pọ̀lọpọ̀ ará ìlú, gẹ́gẹ́ bí àtúnyẹ̀wò òfin tàbí ètò ìsúná ọdọọdún. Ó gba àwọn ẹgbẹ´kan ará ìlú láàyè láti sọ ẹ̀hónú àti nǹkan tí wọ́n fẹ́ sí àwọn asòfin. Ìpàdé ìgbọ́ràn gbogbogbò nílò ìfọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò àti ìfarabalẹ`pẹ̀lú ọ̀wọ̀ láàrin àwọn asòfin, àwọn osìṣẹ́ ìjọba, àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn àti àwọn ará ìlú.

Àwọn ará ìlú le kópa àti ṣe ìyàtọ̀ ńlá akoko àti lẹ́yìn ìgbọ́ràn gbogbogbò lakọkọ, laśìkò ìgbọ́ràn gbogbogbò, a lè fi ìwé ìrántí kan sílẹ̀ èyí tí ó ń ṣafihàn àwọn ọ̀rọ̀ tí ó nílò àmójútó ní kiǎkíá àti àwọn ẹ̀ka tí a nílò láti parẹ́. Ìgbìmọ̀ náà yóò fàyè gba àwọn tí ó bá fifẹ´hàn láti sọ̀rọ̀. Àwọn ènìyàn tó nífẹ̀ẹ́ sí i, àwọn lẹ́gbẹ́lẹ́gbẹ́, lájọlájọ le fi èrò wọn ránṣẹ´nípa lílo ẹ̀rọ ayélujára.

## Àwọn Ọnà Wo Ni Àwọn Ará Ilú Le Kópa Nínú Ìpàdé Ìgbọ́ràn Gbogbogbò

01 Wá àlàyé nínú àwọn ìwé ìròyìn, ìpolówó lórí tẹlifíṣàn, àwọn ìpolówó lórí rédíò, tàbí ojú òpó ìdọ́rẹ̀ẹ́ láti mọ ìgbà àti ibi tí ìpàdé ìta gbangba ti ń waýé.

02 Ṣe ìfitónilétí ìwé àṣẹ tí ó yẹ ki´o jíròrò àti gba ẹ̀dà ìwé òfin (Ní ilé ìgbìmọ̀ asòfin ti ìjọba àpapọ̀ àti ilé asòfin ti ìpínlẹ̀)

03 Ṣe ìdánimọ`àwọn ọ̀rọ̀ tó ṣe kókó kí o sì ṣe àgbékalẹ`àwọn ìmọ̀ràn rẹ ní ìbámu pẹ̀lú àwọn ọ̀rọ̀ náà. O tún lè ṣàfikún ọ̀rọ̀ kan tí o rò pe´ó yẹ kí o kojú èyí tí wọn kò fi kun tẹ̀lẹ̀.

04 Ṣètò ìwé ìrántí kan èyí tí ń ṣàlàyé èrò rẹ àti ibi tí iṣẹ´dúró. Fi ẹ̀dà rẹ sílẹ̀ ṣaájú ìgbọ́ràn gbogbo ènìyàn.

05 Lọ sí ìgbọ́ràn gbogbo ènìyàn kí o sì ṣe àfihàn èrò rẹ.

## Njẹ́ Àbájáde Ijíroro Náà Le Yí Nnkan Pada?

Bẹ́ẹ̀ ni nípasẹ̀ ìgbéláruge, iparowa, fífọwọ́sí ìwé ẹbẹ̀, ìwọ́de àlàáfíà, àti ìjíròrò mìíràn àti gbígbé ìbéèrè lórí àwọn asòfin.

## Àdàkọ Ìwé Iránṫí

Àwọ̀ṣe ìwé iránṫí yìí jẹ́ ìtọ́sọ́nà láti ṣe ìrànlọ́wọ́ fún /tàbí àjọ rẹ tí o bá fẹ́ ṣe ìwé iránṫí.

Orukọ rẹ àti orukọ àjọ rẹ

Àdírẹ́sì

Nọ́ḿbà fóònù rẹ/Àdírẹ́sì ímeèlì rẹ

**Ọrọ Àsọṣáájú**

Ẹ̀yí gbọdọ̀ ní alaye nipa ìwọ/ẹgbẹ́ rẹ, àjọ rẹ, ìdí tí ìwọ/ẹgbẹ́ rẹ/àjọ rẹ ṣe nífẹ̀ẹ́ nínú àbádòfin naâ, ṣe àfihàn àwọn ohun pàtàkì àti ibi tí iṣẹ́ dé dúró, kí o sì ṣàlàyé ìdí tí àtúnṣe tí o dábàá ṣe ṣe kókó. Tí o bá rò wí pé àtúnṣe naâ kò ṣe kókó, o lè yannana rẹ̀ kí o sì ṣàlàyé ìdí tí kò fi ṣe kókó.

Ìmọ̀ràn:- Rí i dajú wí pé o sọ ọ́ ní ṣókí kí o sì lọ sí kókó ọ̀rọ̀.

Aŕiyaǹjiyaǹ àti ibi tí iṣẹ́ dé duró.

Abala yìí yóò ṣe àkójọpọ̀ ìwọ/ẹgbẹ́ rẹ/àbá àtúnṣe ti àjọ rẹ, àríyànjiyàn fún/lórí àbádòfin tàbí ọ̀rọ̀ kan. O gbọdọ̀ pèsè ìmúsédúrú fún àbá láti ṣe àtúnṣe tàbí ṣe ìyọkúrò ọ̀rọ̀ kan tàbí abala kan tàbí ṣe àfihàn ọ̀rọ̀ kan tàbí abala kan nínú ìwé òfin tàbí àbádòfin.

**Ìmọ̀ràn:-** Rí i wí pé o rántí láti sọ bí wọ́n ṣe sọ/dárúkọ àwọn abala tí ó ṣe kókó láti mú aŕiyaǹjiyaǹ rẹ lẹ́sẹ̀ nílẹ̀.

**Ìkádìí**


Abala yìí ṣe àkótán ìwọ/ẹ̀gbẹ́ rẹ/ipò àjọ rẹ àti ìdí tí àwọn àjọ tí ọ̀rọ̀ náà kàn gbọdọ̀ gba ìmọ̀ràn rẹ wọlé.

# Ìmọ̀ràn Lórí Bí Ó Ṣe Le Ṣe Àgbékalẹ̀ Rẹ Nínú Ìgbọ̀gàn Gbogbogbo



## Ikíni

Bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú yíyẹ́ àwọn aṣòfin ati àwọn ènìyàn pàtàkì mìíràn sí (èyí le pẹ̀lú àwọn ilé iṣẹ́ ìjọba ti´wọ́n ṣojú, àwọn èkàn láwùjọ, iléeṣẹ́ ìròyìn ati ará ìlú) ti´ wọ́n wà ní ìkàlẹ̀` níbi ìpàdé ita gbangba. Àmọ́ sá, tí o kò bá lè yẹ́wọn sí dáadáa, ó rọrùn láti ṣe ìkíni gbogbogbò kí ó sì sọ pé: "ẹ gba mí láàyè láti dúró lórí ìlànà ìkíni tí a ti fi ìdí rẹ`múlẹ̀ tẹ́lẹ̀" tàbí "ẹ gbà mí láàyè láti dúró lórí ìlànà tí ó wà tẹ́lẹ̀".



## Ṣe àfihàn ara rẹ àti àjọ rẹ/ẹgbẹ́

Dárúkọ rẹ, àjọ rẹ ati ipò ti´o dìmú. Ti´o bá ń sọ̀rọ̀ fúnra rẹ, orúkọ rẹ ni yóò jẹyọ.



## Ṣe ìdánimọ`ọ̀rọ̀ náà ni ṣókí,

Tọ́ka sí àwọn gbólóhùn ọ̀rọ̀, àwọn apákan tàbí àwọn agbègbè kan nínú àkọsílẹ̀ rẹ. Ṣe àtòpọ̀ àwọn ibi tí iṣẹ́ dúró tí o dábàá. Àwọn ìgbọràn ṣabà máa ń ni àtòpọ̀ gígùn àwọn àjọ tí a ṣètò láti sọ̀rọ̀. Jẹ́ kí àgbéjáde rẹ kúrú, kí ó sì rọrùn. Nígbà mìíràn, láti rí i wí pé àwọn ènìyàn kópa díẹ̀`sí, wọ́n lè fún àwọn ènìyàn ti´ yóò sọ̀rọ̀ ni ìṣẹ́jú mẹ́ta sí márùn-ún láti sọ̀rọ̀. ṢE É NÍ KÚKÚRÚ. SÁFOJÚSUN LÓRÍ ÀWỌN KÓKÓ TÓ ṢE PÀTÀKÌ LÓRÍ ÀRÍYÀNJIYÀN RẸ TÀBÍ ÌMỌRÀN RẸ



## Ìkádìí

Dúpẹ́´lọ́wọ́´àwọn aṣòfin ati àwọn èrò ìwòran fún títẹ́tí sí ọ. Parí pẹ̀lú ìpe sí iṣẹ,́ àpẹẹrẹ ni. "Mo" nírètí wí pé ìgbìmọ`yìí yóò gbèrò gbogbo àwọn ìfisílẹ̀`tí ó wà nínú àkọsílẹ̀ yìí ati fún àwọn ọmọ orílẹ̀ èdè Nàìjíríà ní ìwé òfin ti´gbogbo wa fi le yangàn.

# Ìbáṣepọ̀ Àwọn Ará Ìlú Ati Mímú Àwọn Ìjọba Jábọ̀ Lórí Ojúṣe Wọn Nípasẹ̀ìpàdé Àwọn Agbègbè Ní Gbọ̀ngàn Ìlú

Ìpàdé gbọ̀ngàn ìlú jẹ́ ìpàdé gbogbo ènìyàn fún aỳíká àwọn kókó ọ̀rọ̀ tó ṣeni ní àǹfààní. Fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún, àwọn ìpàdé gbọ̀ngàn ìlú ti jẹ́ ohun èlò pàtàkì fún fífitó àwọn ará ìlú létí nípa àwọn ọ̀rọ̀ tó súyọ, wọn ibi tí àwọn agbègbè kan dúró lórí àwọn kókó ọ̀rọ̀ kan àti ṣíṣẹ́ bí àyè láti ṣe ìdánimọ̀ àti ìmúṣẹ àwọn ojutùú sí ìṣòro kan. Àwọn ìpàdé yìí tún ń ṣiṣẹ́ bí i ọ̀nà ńlá láti gbà fi ọ̀rọ̀ ránṣẹ́ sí àwọn ènìyàn, ṣe aỳbéjáde àwọn ìròyìn, bẹ̀rẹ̀ akitiyan ìpolongo agbègbè nípa kíkójọpọ̀ àti síṣètò àtìlẹ́yìn fún agbègbè ati ṣe ìdámọ̀ àwọn ènìyàn kọ̀ọ̀kan àti àwọn lájọlájọ fún àwọn àjọṣepọ̀ àti ìfọwọ́sowọ́pọ̀ ọjọ́ iwájú.

## Síṣètò Ìpàdé Gbọ̀ngàn Ìlú

ÌGBÉSẸ̀ 01

### Ṣe Àgbékalẹ̀ Àwọn Ìgbìmọ̀ Tí Yóò Ṣètò

Ìpàdé gbọ̀ngàn ìlú jẹ́ ìpàdé gbogbo ènìyàn fún aỳíká àwọn kókó ọ̀rọ̀ tó ṣeni ní àǹfààní. Fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún, àwọn ìpàdé gbọ̀ngàn ìlú ti jẹ́ ohun èlò pàtàkì fún fífitó àwọn ará ìlú létí nípa àwọn ọ̀rọ̀ tó súyọ, wọn ibi tí àwọn agbègbè kan dúró lórí àwọn kókó ọ̀rọ̀ kan àti ṣíṣẹ́ bí àyè láti ṣe ìdánimọ̀ àti ìmúṣẹ àwọn ojutùú sí ìṣòro kan. Àwọn ìpàdé yìí tún ń ṣiṣẹ́ bí i ọ̀nà ńlá láti gbà fi ọ̀rọ̀ ránṣẹ́ sí àwọn ènìyàn, ṣe aỳbéjáde àwọn ìròyìn, bẹ̀rẹ̀ akitiyan ìpolongo agbègbè nípa kíkójọpọ̀ àti síṣètò àtìlẹ́yìn fún agbègbè ati ṣe ìdámọ̀ àwọn ènìyàn kọ̀ọ̀kan àti àwọn lájọlájọ fún àwọn àjọṣepọ̀ àti ìfọwọ́sowọ́pọ̀ ọjọ́ iwájú.

ÌGBÉSẸ̀ 02

### Ṣe Ìwádìí Ohun Àmúyẹ Pàtàkì Ti Agbègbè Rẹ

Kí o tó ṣètò ìpàdé gbọ̀ngàn ìlú rẹ, ó ṣe pàtàkì láti ní òye nípa àwọn ìṣòro aláìlẹ́gbẹ́ tí ìlú rẹ ni, àwọn italaya ati àwọn àǹfààní fún ìyípadà. Ṣe àtúnyẹ̀wò àwọn ọ̀rọ̀ tó wà nílẹ̀ tẹ́lẹ̀ láti onírúurú orísun kí o sì ṣe àgbékalẹ̀ ìpò agbègbè rẹ èyí tó dálé lórí ìwádìí tó yanrantí. Àlàyé yìí yóò ràn ọ́ lọ́wọ́ bí ó ṣe le dojúkọ ìjíròrò náà kí o sì fún ètò ati àgbékalẹ̀ rẹ ni òṣùbà o kaŕe.

ÌGBÉSẸ̀ 03

### Ṣe ìdánimọ̀ àwọn èròǹgbà

Kò sí ìpàdé gbọ̀ngàn ìlú méjì tí ó jọ ara wọn. Àkóónú ìpàdé rẹ, ọ̀nà àti kókó ìpàdé rẹ yóò dálé lórí àwọn ọ̀rọ̀ kan tí ẹ fiyèsí àti àwọn ìwúlò tí ìwọ ati àwọn akẹgbẹ́ rẹ ti ṣe ìdánimọ̀ rẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, ìpinnu rẹ le jẹ́ láti sọ fún àwọn ọmọ ẹgbẹ́ agbègbè rẹ nípa ìṣòro ní agbègbè rẹ. Àwọn agbègbè mìíràn le fẹ́ kí ìpàdé gbọ̀ngàn ìlú wọn jẹ́ àpéjọ fún ìpè sí iṣẹ́, bíi ìmúgbòòrò bá ètò ilera, ètò ẹ̀kọ́ tàbí àwọn ohun amáyédẹrùn.

# Síṣe Ìpàdé Gbọngàn Ìlú Rẹ

ÌGBÉSẸ̀ 01

### Ṣíṣètò ìpàdé rẹ.

Láti rí i dájú wí pé o ṣe àṣeyọrí fún ètò rẹ, yan àwọn ọmọ ẹgbẹ́agbègbè àti àwọn afarajìn lọ́fẹ̀ẹ́ sí oríṣiríṣi àwọn iṣẹ́ ṣíṣe.

**Síṣètò:-** Díẹ̀ nínú àwọn ènìyàn gbọdọ̀dé ní kùtùkùtù láti rí i wí pé ibi gbọ̀ngàn ìpàdé (bí i àárín ìlú, gbọ̀ngàn ìgbàlejò tàbí abẹ́igi) ti dúró dáadáa àti láti ṣe àwọn àtúnṣe tí ó bá yẹ kí ètò tó bẹ̀rẹ̀. Fún ìpàdé nlá o lè nílò láti ní ẹ̀rọ amóhùndúngbẹ̀mù, pẹ̀lú àwọn gbohùngbohùn torí tábìlì fún àwọn alámọ̀dájú, ìpàdé kékeré pẹ̀lú àwọn olùkópa márùndínlọ́gbọ̀n tàbí díẹ̀, ṣiṣẹ́ dáadáa pẹ̀lú ìsètò oní ìyípo.

**Wíwọlé/Tábìlì ìforúkọsílẹ̀:-** Ìwọ yóò nílò láti ṣètò tábìlì ìwọlé, nibi tí o ti le gba àwọn orúkọ àti àlàyé olùbásọ̀rọ̀ fún gbogbo ènìyàn ti ó wá tí wọ́n sì fi ohun èlò sílẹ̀. Rántí láti ní ìwé ìwọlé ọlọ̀tọ̀ọ̀tọ̀, ọ̀kan fún gbogbo ènìyàn ati ọ̀kan fún àwọn ọmọ ẹgbẹ́ oníròyìn. Àlàyé yìí yóò ṣe pàtàkì bí o ṣe n ṣe àwọn iṣẹ́ àtẹ̀lé rẹ àti gbèrò ìpàdé ọjọ́ ìwájú.

**Àwọn ìwé aláfọwọkọ:-** Nibi tábìlì ìforúkọsílẹ̀o lè fẹ́ láti ní àwọn èrò ati àlàyé mìíràn, pẹ̀lú ohun èlò iṣẹ́ fún àwọn ajábọ̀ ìròyìn. ti o bá gbèrò láti jíròrò nípa àwọn ìwé àṣẹ kan, rí i wí pé, àwọn ẹ̀dà rẹ wà nílẹ̀.

ÌGBÉSẸ̀ 02

### Sísàkóso ìpàdé rẹ

Ìpàdé náà yẹ kí ó bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú ìkíni àti ìtẹ́wọ́gbà láti ọwọ́ àwọn ìgbìmọ̀tó ṣètò ìpàdé gbọ̀ngàn ìlú tàbí ìgbìmọ̀ètò. Ikíni káàbọ̀ àti Ìfihàn kò gbọdọ̀ju ìṣẹ́jú márùn-ún lọ kí o sì ṣàlàyé ìdí ìpàdé náà, kí àwọn alejò káàbọ̀ kí o sì ṣàfihàn adarai ètò. Adari ètò wá gbọdọ̀bẹ̀rẹ̀ ìpàdé gbọ̀ngàn ìlú pẹ̀lú àlàyé ránpẹ́ lórí àwọn ìṣòro ti wọn yóò mẹ́nubà, àyẹ̀wò ìtolẹ́ṣẹẹṣẹ àti àfihàn àwọn tí yóò sọ̀rọ̀ lọ́kọ̀ọ̀kan. Ó máa ń dára láti jẹ́ kí gbogbo àwọn onímọ̀ sọ̀rọ̀, lẹ́yìn náà dáhùn ìbéèrè láti ọ̀dọ̀ adarí ètò. Gbogbo ìjíròrò àwọn onímọ̀orí tábìlì kò gbọdọ̀ju àádọ́ta ìṣẹ́jú lọ. Lẹ́yìn ìjíròrò àwọn onímọ̀orí tábìlì, olùdarí ètò gbọdọ̀bẹ̀rẹ̀ àkọ́kọ́ ìbéèrè ati ìdáhùn. Lẹ́yìn ìbéèrè ati ìdáhùn, yálà olùdarí ètò tàbí agbàlejò gbọdọ̀kásẹ̀ ìpàdé pẹ̀lú dídúpẹ́ lọ́wọ́ gbogbo ènìyàn fún wíwá wọn. Gba àwọn olukópa níyànjú láti gbé ìgbésẹ̀àkọ́kọ́ iṣẹ́ kan, bí ó tilẹ̀ wù kó kéré tó. Ṣe ìwúrí fún àwọn tó nífẹ̀ẹ́ sí ṣíṣe ìtọ́ṣọ́nà, kọ́ àti ṣètò ẹgbẹ́ kékeré kan láti ṣe àwọn iṣẹ́ díẹ̀. Pèsè àlàyé olùbásọ̀rọ̀ fún àwọn tó fẹ́ bá a lọ lẹ́yìn ìpàdé.

ÌGBÉSẸ̀ 03

### Sàkóso ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò àwọn oníròyìn.

Fi ààyè tí ó tó sílẹ̀ fún ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò fún àwọn oníròyìn. Lẹ́yìn gbogbo ètò, ó yẹ kí o yọ ọgbọ̀n ìṣẹ́jú sílẹ̀ lẹ́yìn ìgbà tí àkọ́kọ́ ìbéèrè àti ìdáhùn bá parí láti mójútó àwọn ifọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò láàrin àwọn ọmọ ẹgbẹ́ oníròyìn ati àwọn agbẹnu sọ̀rọ̀ rẹ. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà, àwọn oníròyìn yóò bèrè ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò ọjọ́ iwájú, rí i wí pé ẹnìkan wà nílẹ̀láti yanjú ìbéèrè fún ifọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò àwọn oníròyìn.

## Lẹ́yìn Ìpàdé: Kí Ló Kàn Látìṣe

Gbogbo akitiyan rẹ kò parí pẹ̀lú ìpàdé gbọ̀ngàn ìlú. Ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà, ìpàdé ń ṣiṣẹ́ gẹ́gẹ́ bí i ayáṣẹ̀ fún àwọn ìlànà àti ìpilẹ̀ṣẹ̀ ọjọ́ iwájú. Láti ṣe àṣeyọrí èrò rẹ, ìwọ yóò nílò láti gbé àwọn ìgbésẹ̀ àtẹ̀lé ní àwọn ọ̀sẹ̀ díẹ̀ lẹ́yìn ìpàdé náà.

ÌGBÉSẸ̀ 01

### Ṣe Ìfọ̀rọ̀wọ́rọ̀

Kò ju ọ̀sẹ̀ méjì lọ lẹ́yìn ìpàdé gbọ̀ngàn ìlú, ṣe àpéjọ àwọn ènìyàn pàtàkì ti´wọ́n ní ipa nínú síṣètò náà láti jíròrò lórí bí o ṣe lọ. Ṣe ìjíròrò bóyá ẹ ṣe àṣeyọrí àwọn ibi afẹ́dé rẹ ati bí o ṣe fẹ̀ fi àwọn àlàyé àti àwọn èrò ti´ó farahàn sí iṣẹ́ ṣíṣe ní agbègbè.

ÌGBÉSẸ̀ 02

### Ṣe àgbékalẹ̀`ètò iṣẹ´kan

Lẹ́yìn ìfitónilétí, kọ àwọn àsọyé láti ibi ìpàdé gbọ̀ngàn ìlú, sísọ àfojúsùn ìfitónilétí náà ati yíyán àti ṣíṣe àkópọ̀ àwọn ìṣòro ati ojútùú tí àwọn olùgbé agbègbè àti onímọ̀ fún ni. Ronú nípa àwọn ohun ti ìgbése`àtẹ̀lé le jẹ́ kí o sì ṣe àgbékalẹ̀`èrò iṣẹ´ṣíṣe. Díẹ̀ nínú àwọn èrò jẹ´ ètò àmúlò, ìtànkálẹ` àlàyé tàbí ìpolongo àwọn oníròyìn.

ÌGBÉSẸ̀ 03

### Lílo àwọn ìpàdé gbọ̀ngàn ìlú láti mú àmúgbòòrò débá iṣẹ´ìpolongo rẹ

Ọkan nínú àwọn ohun èlò ti´ó wúlò julọ tí o lè ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀ láti ibi ìpàdé rẹ ni atòpọ̀ orúkọ àti àlàyé olùbásọ̀rọ̀ gbogbo àwọn tó kópa. Ìpamọ´àwọn orúkọ yìí le di atokọ ifiwéránṣẹ́ rẹ fún àwọn ìṣẹlẹ̀ ọjọ́ iwájú àti orísun tí àwọn alátìlẹyìn ati àwọn olùyọ̀nda. Ibi ìpamọ´ orúkọ yìí tún le jẹ´orísun láti ṣe ìdánimọ`àwọn ènìyàn ti´ó le nífẹ̀ẹ́ láti fọwọ́ sí àwọn ẹ̀bẹ̀ fún wíwá sí àwọn ìgbọ̀ràn gbogbgo ènìyàn.

# Ìbáṣepọ`Àwọn Ará Ìlú Ati Mímú Àwọn Ìjọba Jábọ`Lórí Ojúṣe Wọn Nípaṣẹ  Ìwé Ẹbẹ̀

Ẹbẹ`jẹ´ọ̀nà kan ti´ó tayọ láti ṣe iyipada`ti´ó níláárí ní àgbáyé. Bóyá ó jẹ´ọ̀rọ` àgbáyé ti´ó nípọn tàbí ìdìbò agbègbè ti´ó rọrùn, ẹ̀bẹ̀ le gba àlàyé rẹ kọjá àti gbé àbájáde gidi. Lákòókò ti´o ṣẹ̀dá ìwé ẹbẹ̀, ó lè dàbí ohun tí ó léwu àti iṣẹ́ tí ó lágbára, ó rọrùn púpọ`láti beèrè. Gbogbo ohun ti´o nílò láti ṣe ni yan àwọn ìtàkùn tó tọ́, kọ ìpèsẹ̀jọ́ rẹ, kí o sì jẹ´kí àwọn olùgbọ́ rẹ fọwọ́ sí i.

Ṣe ìdánimọ`èrò rẹ ati àwọn olùgbọ́ tí o fẹ́. Gbogbo ipesẹjọ lọ ni èrò wọn, olùgbọ´àti atọ́ka ìyípadà tí o fẹ́ rí. Mímọ ohun tí o fẹ́ yípadà àti ẹni tí o nílò láti rí ti´yóò ṣe iranlọ́wọ́ púpọ̀ fún ọ bí o ṣe ń ṣe àgbékalẹ̀ rẹ.

**Ikani jẹ́ ọ̀nà tí o ṣẹ̀dá láti pín ìwé ẹbẹ̀. Láti yan ìkànì, ó yẹ kí o ronú nípa tani o nílòò láti dé ọ̀dọ̀ rẹ̀ àti ohun tí o fẹ́ yi padà.**

**Díẹ̀ nínú ilé iṣẹ́ ìjọba ati àwọn iléeṣẹ́ nílò àwọn nọ́mbà ìbuwọlù kan ṣaájú kí wọ́n tó kàwọ́ sí ẹ̀bẹ̀. Rí i dájú pé o ṣàyẹ̀wò sí wọn láti mọ ikani ti´ wọ́n gbà láàyè àti iye ìbuwọlù tí ìwọ yóò nílò kí o tó bẹ̀rẹ̀.**

## Yàn láàrin ẹbẹ`orí ayelujara tàbí alátẹjáde ní ìbámu pẹlú ìwúlò rẹ:

**Yíyẹ pẹpẹ ti´ó yẹ yóò rí i dájú pé àwọn olùgbọ´tí ó tó ń rí àti fọwọ́ sí ìwé ẹbẹ̀ rẹ. Ìtàkùn ayelujára tí o bá jẹ́ kí ó dé ọ̀dọ̀ àwọn ènìyàn káàkiri orígun mẹ́rẹ̀ẹ̀rin àgbáyé. Lọ àwòse kan láti tẹ àwọn ẹ̀dà ti ojúkorojú jáde tí o bá ń gbìyànjú láti rawọ´ẹ̀bẹ̀ sí àwọn olùgbé agbègbè rẹ.**

**Ó rọrùn púpọ̀ láti rí àwọn ènìyàn láti fọwọ´sí ìwé ẹbẹ̀ rẹ tí o bá le ṣàfihàn rẹ̀ fúnra rẹ àti ṣe àlàyé ìdí rẹ` fún wọn. Gbèrò títẹ ìwé ẹbẹ̀ rẹ àti fífihàn sí gbangba fúnra rẹ.**

## Lọ pẹpẹ kan láti ṣẹ̀dá ìwé ẹbẹ̀ ayélujára:

**Àwọn ojú òpó wẹ̀ẹ̀bù tó gbajúmọ̀ ló wà tí o lè fi ṣẹ̀dá ẹ̀bẹ̀. Change.org/Gopetition.com, àti ipetitions jẹ́ àwọn ẹ̀rọ orí ayélujára tí ó rọrùn tí ó gbà ọ́ láàyè láti ṣẹ̀dá àti pín ohun ẹ̀bẹ̀ Ọ̀fẹ́ ni láti lò, ṣùgbọ́n wọ́ níohun àṣàyàn tó níye tí o bá dé ibi àti ṣe ẹ̀bẹ̀.**

Ni ìbámu pẹlú change.org[4]. Ìwé ẹ̀bẹ̀ jẹ́ ìwé kíkọ ti´ó ń bèèrè díẹ̀ nínú àyípadà tàbí ẹ̀bẹ̀ sí àwọn tí ó wà nipo àṣẹ. Gbígba ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìbuwọ̀lù láti ọ̀dọ̀ onírúurú ènìyàn ṣe afihàn ìwọ̀n àtìlẹ́yìn fún ìdí ti´o ṣe ṣé.

**Ìlànà ìpìlẹ`fún sísẹ̀dá ẹ̀bẹ̀ ni:**




---

4 https://guide.change.org/create-a-petition

## Yan orí ọrọ̀`rẹ

Ìgbésẹ̀`àkọ́kọ́ níbi ṣísẹ̀dá ìwé ẹbẹ̀ ni láti yan kókó kan tí o ní ìtumọ̀ sí ọ. Tí o kò bá ní iṣẹ́kan pàtó lọ́kàn, bẹ̀rẹ̀ nípa ríronú nípa àwọn ohun àmúgbòòrò ti´o wù ọ́, bíi ìwà dáadáa àwọn ẹranko. Lẹ́yìn náà, ronú nipa bí o ṣe lè dín ọ̀rọ̀ rẹ kù sí iṣẹ́ kan pàtó. Ṣe ètọ́ fún nǹkan tí o fẹ́rí nìkan, ṣùgbọ́n tún ṣe bí o ṣe lè ṣe àṣeyọrí àti wọn àṣeyọrí náà. Àwọn àlàyé kíkún dára jùlọ; o fẹ́ pe àkíyèsí àwọn olùka rẹ̀ àti láti pàrọwà fún wọn láti fọwọ́ sí ìwé ẹ̀bẹ̀ rẹ. Nípa yíyan kókó ọ̀rọ̀ pẹ̀lú àwọn ìgbésẹ̀`tó hàn, ìwọ yóò ṣètò ara rẹ fún ìpolongo ìwé ẹbẹ̀ tí ó ní àṣeyọrí tí ó sì ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìbuwọlù.

## Kọ àkọlé rẹ

Àkọlé rẹ ni àǹfààní àkọ́kọ́ láti lè jẹ́ kí àwọn olùka rẹ ṣe alábàpín ìwé ẹ̀bẹ̀ rẹ kí o sì ṣàlàyé iyípadà tí o fẹ́ dárúkọ àwọn ààyè kan pàtó, àwọn àjọ tàbí àwọn ènìyàn. Àwọn alátìlẹyìn yìí fẹ́mọ̀ bóyá ìwé ẹbẹ̀ ní í ṣe pẹ̀lú wọn tàbí agbègbè wọn. Dídárúkọ àwọn agbègbè tí wọ́n ti ní ipa yóò gba akíyèsí. Ṣe àkíyèsí nípa lílo álífábẹ́ẹ̀tì òkè tàbí afikún àmì (!!!) èyí ti´o le túmọ̀ àkọlé gẹ́gẹ́ bí i èyí tí o ní ìtara àti wí pé o lè má wuyì sí àwọn alátìlẹyìn.

## Bẹrẹ pẹlú ọrọ-ìṣe

Àwọn olùkà fẹ́ láti mọ̀ ní pàtó irú àyípadà tí o fẹ́ ṣe kí wọn lè pinnu bóyá wọn yóò fọwọ́sí ìwé ìpẹ̀jọ́ rẹ. Àkọlé rẹ ni ọ̀nà láti dojúkọ ojútùú náà. Àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe ti´ o wọ́pọ̀ fún ìpẹ̀jọ́ ni "dúró, rànlọ́wọ́, gbẹ́sẹ̀lé, fifúnni, takò, fikún, bẹ̀rẹ̀".

## Lọ ìkọ́

Gba àkíyèsí àwọn ènìyàn nipa ṣíṣe àkọlé rẹ nípò ẹ̀dùn àti ìyára. Jẹ́kó yé wọn ẹni tí o kan àti ìdí ti´o fi bìkítà. Ti´àwọn déètì tàbí àkókò tó ṣe kokó bá wà níbi ìwé ẹbẹ̀ rẹ, ṣe àfikún àlàyé náà.

## Yan Onípinu rẹ̀

Onípinu jẹ́ ẹnìkan ti´ó wà nípò àṣẹ ti´ó ní agbára láti ṣe ìrànlọ́wọ́ láti ṣe ìyípadà tí ò ń wá. Èyí le pẹ̀lú olóṣèlú, gbajúmọ̀, tàbí oníṣòwò. Ní kété ti´o bá ti ní èròǹgbà fún ẹ̀bẹ̀ rẹ, o lè mọ ẹni tí (tàbí àwọn ènìyàn) ti´o gbọdọ̀ jẹ́. Fún àpẹẹrẹ, àwọn aláṣẹ tí a yàn le ṣe ìrànwọ́ pẹ̀lú ọ̀rọ̀ òfin, nígbà tí olùdarí ìṣòwò le ṣe ìrànwọ́láti ṣe àyípadà ní ẹ̀ka aladan.

## Kó àwọn àlàyé jọ nípa onípinu tí o yan nínú ìwé ẹbẹ rẹ

Nípa fífi ímeèlì àdìrẹ́sì fún àwọn onípinu ti´o tọ́ o lè jẹ́ kí wọ́n mọ̀ nípa ìpẹ́jọ́ rẹ kí o fún olùkà ní ìgboyà pé ẹ̀bẹ̀ rẹ yóò jáwé olúborí.

## Yan ènìyàn, kì í ṣe ẹgbẹ´tàbí àjọ

Yàtọ̀ sí àjọ, o lè mú àwọn ènìyàn jíjìn taȁrà. Ṣe onípinu rẹ ní ènìyàn tàbí àwọn ènìyàn láàrin àjọ kan ti´wọ́n ti wọ́n jẹ́ onídùúró fún ojútùú rẹ tàbí ẹni tí o lè pàrọwà fún. Bí àpẹẹrẹ: “Honorable John Brown” dípò (Ìjọba àpapọ`orílẹ̀-èdè Nàìjíríà.

## Yan ẹnìkan ti´o jẹ́ onídùúró taarà

O dára láti fojúsí àwọn ènìyàn ti´o lè fún ọ ní ohun tí o fẹ́ ju ẹni tó jù ọ́ lọ, àwọn sànkòsànkò láwùjọ. Ẹni ti´ó jẹ́ onídùúró tàárà le ṣe ìpinnu àti ṣe ìmúṣẹ ojutùú rẹ ní ọ̀nà tó yára. Wọ́n tún ní díẹ̀ sí títẹ̀ gbangba nítorí wọn kò ní iȉrírí rẹ̀.

## Sọ ìtàn rẹ

Sísọ ìtàn wà ní àárín gùngùn níní ẹ̀bẹ̀ tí ó yọrí. Ẹ̀rí, ìṣirò, ìtọka jẹ́ ìrànlọ́wọ́ láti ṣàfikún, ṣùgbọ́n tún ronú pínpín ìrírí ẹni kọ̀ọ̀kan tí o ṣe ìrànlọ́wọ́ fún ènìyàn pẹ̀lú ẹ̀dùn ọkàn sí ìdí rẹ. Wo yíyan ọ̀rọ̀ rẹ àti ohun ní ìtọka sí àwọn olùgbọ́ rẹ. Bí àpẹẹrẹ, o lè dojúkọ àwọn òbí ti´ẹ̀bẹ̀ rẹ bá dá lórí ìdí kan bí: ìlera ìyá tàbí ẹtọ́ ẹ̀kọ́ ọmọdé. Ronú nípa iye wọn àti pàtàkì rẹ`àti bí o ṣe ní ìbátan sí ìṣòro ti´o nírètí láti yanjú. O tún le lo fídíò láti gba akíyèsí àwọn olùgbọ́ rẹ. Àti wí pé o kò ní lò láti ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ nǹkan láti sọ ìtàn ti´ó dára. Pẹ̀lú kámẹ́rà fóònù ati díẹ̀ nínú sọfitiwia ọ̀fẹ́ tí ó ń sàtúnkọ fídíò, o lè ṣàfihàn ìfẹ´tìẹ, kí o sì gba àwọn mìíràn níyànjú láti ní ìmọ̀lára ní ọ̀nà kan náà bí ìwọ.



## Ìbáṣepọ̀ Ará Ìlú Ati Mímú Ìjọba Jábọ̀ Lórí OjúṣeWọn Nípa Ilé Ẹjọ́

Gẹ́gẹ́ bí ọmọ ẹgbẹ Ìparapọ̀ àwọn orílẹ̀-èdè (United Nations) àti Ìparapọ̀ Àwọn Orílẹ̀-èdè Áfíríkà tí fọwọ́sí àwọn ohun èlò ẹtọ́ ọmọnìyàn pàtàkì lágbàáyé tó ń wá láti dáàbò bo àti láti gbé ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn lárugẹ àti òmìnira pàtàkì. Láìṣeyèméjì, ìmúnádóko àwọn ẹ̀tọ́ tí o ní ìdánilójú nínú àwọn irinṣẹ́ wọ̀nyí àti òfin orílẹ̀-èdè Nàìjíríà gbáralé ìwọ̀n ńlá lórí wíwá àwọn èrò ati àtúnṣe fún ìmúṣẹ wọn.

Àwọn ilé ẹjọ́ kó ipa pàtàkì nínú ààbò ẹtọ́ àwọn ènìyàn ni Nàìjíríà. Ilé ẹjọ́ jẹ́ ètò to ní òfin tí ó ṣe pàtàkì julọ tí a ṣètò láti rí i wí pé wọ́ tọ́jú àti wà ní ìbámu pẹ̀lú àwọn ilànà ẹ̀tọ́ ènìyàn tí ó ti wà ní ìpamọ́ ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ohun èlò ẹtọ́ àwọn ènìyàn kárí ayé ati ìwé òfin.

Ìbáṣepọ̀ láàrin ìráyè sí ìdájọ́ fún àwọn ọmọ ẹgbẹ́ agbègbè àti àwọn ìdáàbò bo ẹ̀tọ́ ènìyàn yan nibi ẹ̀rí wí pé ó di ìgbà tí àwọn ènìyàn bá ní ànfààní sí kóòtù tí wọ́n le wá ààbò sí àwọn ẹtọ́ ìpìlẹ̀ wọn. Ní gbólóhùn mìíràn ẹ̀wẹ̀, àwọn òfin ati àwọn ẹ̀yà ìgbékalẹ̀ tí ó wà nínú ètò le jẹ́ èyí tí yóò dènà àwọn ará ìlú láti ní ànfààní sí kóòtù, tí wọn kò wá ní ànfààní láti wá ìmúṣẹ tàbí ààbò fún àwọn ẹtọ́ ìpìlẹ̀ wọn.

## Àwọn Ànfààní Fún Ìbáṣepọ Ará Ìlú Nípa Lílo Ọnà Ilé Ẹjọ́

### Igbìmọ̀ iranlọ́wọ́ òfin ti Nàìjíríà[5]

Ìgbìmọ̀ ìrànlọ́wọ́ òfin ti Nàìjíríà ń ṣiṣẹ́ ní gbogbo orílẹ̀ èdè láti pèsè iṣẹ́ òfin ọ̀fẹ́ tí ó dára fún àwọn afurasí, aláìní ati fífún àwọn tí kò ní ohùn ní ohùn. Ìran tí ìgbìmọ̀ ìrànlọ́wọ́ òfin ní ni láti kọ́ orílẹ̀ èdè Nàìjíríà nibi tí déédé wà láti rí ìdájọ́ òdodo fún gbogbo ènìyàn láìbàkítà ọ̀nà àti ibi gbogbo ti wọ́n bọ̀wọ̀ fún ẹ̀tọ́, dáàbò bò ati gbèjà.

[5] https://legalaidcouncil.gov.ng/

## Nigerian Bar Association Human Rights Institute (NBA-HRI)[6]

Àjọ àwọn agbẹjọ́rò Nàìjíríà ti nígbà gbogbo wà ní ipò iwájú fún ìgbéga àti ìdáàbo`bọ̀ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn, ìlànà òfin àti ìṣàkóso rere ní Nàìjíríà. Ilé ìgbìmọ`ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn ti àjọ àwọn agbẹjọ́rò Nàìjíríà (NBA-HRI) ni a dá síle`láti ṣe àgbéga àti dáàbo`bọ`ìlàna`òfin, òmìnira oṣìṣẹ́ amòfin àti láti mú ìmúdúró ẹ̀tọ́ àwọn ènìyàn lọ sí iwájú ní oríle`èdè Nàìjíríà. Yóò ṣe ìgbéga ìbọ̀wọ̀ fún iyì ènìyàn, àti túmọ̀ ẹ̀tọ́ fífi àwọn ìlànà yẹn sí lílò. Ilé ẹkọ́ máa pèsè àwọn ètò ìdàgbàsókè ìmọ` ẹ̀rọ àti pé, ó tún jẹ́ ìlànà ìdàgbàsókè àwọn orísun fún ìpolongo fún ẹgbẹ´ agbẹjọ́rò Nàìjíríà. Ilé ẹkọ́ náà ní tábìlì ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn ní gbogbo ẹka ọ́gọ́fà ẹgbẹ́ agbẹjọ́rò Nàìjíríà káàkiri gbogbo oríle`èdè. Ilé ẹ̀kọ́ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn ní ìpele ẹka ni igbákejì alága ẹgbẹ´agbẹjọ́rò tí ẹka kọ̀ọ̀kan ń darí.

Àfojúsùn ilé-ẹkọ´ẹtọ´ọmọnìyàn ti ẹgbẹ´agbẹjọ́rò (NBA-HRI). Àwùjọ nibi ti´ àwọn ẹtọ´ènìyàn ti ní ìgbéga àti ààbò àti òmìnira òfin wà ni. Àwùjọ tí kò sí ìdíwọ´fún wíwọlé sí ìdájọ´àti ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn àti èyí tí wọn yóò dáàbo`bọ̀ iyì àwọn tó ní ìpalára.

[6] https://nbahri.org/

# Ìbáṣepọ̀Ará Ìlú Ati Mímú Ìjọba Jábọ̀Lórí Ojúṣe Wọn Nípa Ìwé Àdéhùn Ọmọ Ilú

Ìwé àdéhùn ìlú jẹ́ àdéhùn kíkọ láàrin àwọn tí ó níí ṣe (bí àpẹẹrẹ àwọn ìjọba àti àwọn tí wọ́n ń ṣe ìjọba lé lórí) ti ó ń gbèrò láti ṣe afihàn ìjọba ti ó hàn ní gbangba àti jíyìn. Wọ́n jẹ́ àwọn irinṣẹ́ fún ìṣirò awùjọ tí ó bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú àwọn ẹgbẹ́ ọmọ ìlú láti mú àwọn oṣìṣẹ́ ìjọba, àwọn olóṣèlú àti àwọn olùpèsè iṣẹ́ ṣe àkọlé fún ìhùwàsí àti iṣẹ́ wọn ní ìbámu pẹ̀lú ìfijíṣẹ́ iṣẹ́, ojúṣe tí a fún wọn ni àṣẹ, àti àdéhùn gbogbo ènìyàn. Ìwé àdéhùn ará ìlú ni ìfọkànsí láti rí i dájú pé ìbánisọ̀rọ̀ déédé wà láàrin olùdìbò ìlú àti ìjọba kan pató, olóṣèlú tí ó kàn, láti mú àwọn àdéhùn wọn sẹ ní ètò ìdàgbàsókè tí ó ní àsọyé ní gbangba. Ìwé àdéhùn ọmọ ìlú tún jẹ́ ìpinnu láti ṣe ìwúrí fún ọmọ ìlú tó n ṣiṣẹ́ lọ́wọ́, tí ó ń yọrí sí ìbáṣepọ̀ oníwọ̀ntunwọ̀nsì láàrin àwọn olóṣèlú àti ará ìlú, àwọn àjọ àti gbígba àwọn tí kò ní ànfààní ni ààyè láti gbọ́ ohùn wọn nínú ètò ìmúlò àti ìlànà gbígbèrò.

Ìwé àdéhùn ọmọ ìlú ṣe àgbéga olórí tí ó dá lórí iṣẹ́ tí ó ṣe bí àwọn olùdìbò ìlú bẹ̀rẹ̀ sí ní yan àwọn adarí kì í ṣe fún "àwọn ọ̀rọ̀ tó dára", ṣùgbọ́n fún "iṣẹ́ ṣíṣe" àti agbára láti darí àti ṣe akoso. Ìwé àdéhùn ọmọ ìlú n pèsè ìlànà kan èyí tí ìkópa le ṣẹlẹ̀ ní àwọn ìpele oriṣiríṣi tí àwọn ará ìlú le kópa fún àbájáde ti ó dára jùlọ.

Ilana ìwé àdéhùn ọmọ ìlú ní í ṣe pẹ̀lú ìpele márùn-ún ti iṣẹ́ ṣíṣe èyí tí ó tán ká ìgbà kí ètò ìdìbò tó wáyé àti ìgbà lẹ́yìn ètò ìdìbò.

Ìgbà kí ètò ìdìbò tó wáyé

## Ìgbà Kí ètò ìdìbò tó wáyé

### Ìpele kìn-ín-ní: Ìṣàgbékalẹ̀ iṣẹ́ àdéhùn ọmọ ìlú

Ilana náà níí ṣe pẹ̀lú onírúurú àwọn ìjùmọ̀sọ̀rọ̀ pọ̀ apákan ní agbègbè/ipò awùjọ, ó kéré jù oṣù kan ṣaájú bíbẹ̀rẹ̀ ìpolongo ìbò. Ìwé àdéhùn ọmọ ìlú ni a pèsè sílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí Ìfihàn ti àpapọ̀, ìṣọ̀kan àwọn ìfiyèsí pàtàkì ti ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ẹgbẹ́ oníṣòwò bí i àgbẹ̀, àwọn alágbàse, àwọn obìnrin, ọ̀dọ́, àwọn oníṣe ọwọ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ tí wọn kọjú wọn sí àwọn olùdíje sí ipò oṣèlú.

### Ìpele keji: Apero àwọn oludije

Apero n ṣe àkójọpọ̀ gbogbo oludije sí ipò oṣèlú láti fojúkojú pẹ̀lú àwọn ará ìlú agbègbè. Nibi apero, wọn yóò ṣe àgbékalẹ̀ ìwé àdéhùn, wọn yóò sì wá ìdáhùn láti ọ̀dọ̀ àwọn olùdíje.

Wíwá àwọn aṣojú oníròyìn nibi àpérò olùdíje ṣe pàtàkì púpọ̀ láti ṣe ìgbéláruge ìdí náà,, àṣẹ àmúgbòòrò ìtànkálẹ̀ àlàyé sí gbogbo ènìyàn àti láti ṣe ìgbàsílẹ̀ àwọn ìlànà, àwọn àdéhùn tí a fọwọ́ sí àti àwọn àdéhùn tí a ṣe.

## Ìpele kẹta: Ìbuwọlù ìwé àdéhùn

Ìpele yìí ní í ṣe pẹlú fífọwọ́sí ìwé àdéhùn láàrin àwọn olùdìbò ati olùdíje. Ìwé àdéhùn n´ṣe àfihàn àdéhùn tó wà láàrin àwọn olùdíje àti àwọn olùdìbò nípasẹ̀ èyí tí àwọn olùdíje, tí ó bá yàn wọ́, gbà láti ṣe ìjíyìn nípasẹ̀ ìgbeléwọ̀n gbangba tí ń lọ lọ́wọ́.

## Ìgbà lẹ́yìn ètò ìdìbò

Àwọn iṣẹ´ ní ìpele yìí bẹ̀rẹ̀ lẹ́yìn ti´àwọn òṣìṣẹ́ tí wọ́n yàn ti gorí oyè àti ní pàtàkì n´parọwà fún àwọn ìpinnu aṣòfin láti ṣe àgbékalẹ`àwọn ìpèsè ìwé àdéhùn ará ìlú pẹlú àwọn ìpín ìṣúná.

## Ìpele kẹrin: Àmójútó iṣẹ´ìgbeléwọn

Ìdí fún pẹpẹ gbogbo ènìyàn ni láti ṣe ìgbeléwọ̀n iṣẹ́ tí àwọn aṣojú tí a yàn gangan ṣe ìpàrọwà wọn ṣaájú ìdìbò sí èròǹgbà àwọn ènìyàn ati òfin ìwé àdéhùn ará ìlú.

## Ìpele karun-ún: Síṣètò ìwé àdéhùn ọmọ ìlú

Èyí jẹ´ ilana`ti´ó lewu nibi ti´CSOs ti mọ̀ọ̀mọ̀`ati pẹlú ìtara ṣe ìfilọ̀lẹ̀ àwọn ìpolongo láti mú àwọn aṣojú agbègbè láti ṣe àgbékalẹ`òfin fún ìgbekalẹ`ìwé àdéhùn ará ìlú pẹlú ìpín ìṣúná.

## Ànfààní ìwé àdéhùn ọmọ ìlú

Ìwé àdéhùn ọmọ ìlú ṣe ìrànlọ́wọ́ láti ṣe àdínkù ìbàjẹ,́ ìmúdára àkóyawọ,́ ìráyè sí i, ìdáhùn ati ìṣirò ti àwọn olùdíje òṣèlú àti òṣìṣẹ́ ìjọba. Àwọn ìwé àdéhùn ọmọ ìlú tún ti ṣe ìdíwọ´ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn àìsedéédéé bí i ìlòkulò àwọn owó ìlú, ìdádúró fún ìsáǹsá, ètò ti´kò muná dóko, ìṣúná ati iṣẹ́ ṣíṣe àti ìwà àìsedéédéé ti àwọn oṣìṣẹ´ìjọba. Pàápàá ní àwọn ipo`ti´ó ní italaya, ọgbọ́n atinuda´ati ìtẹramọ́ṣẹ́ ti ṣàṣeyọrí nîbi ìlọsíwájú ọ̀nà ìsiṣẹ´ti Ìfihàn gbangba àti àwọn èsì. Àwọn ìwé àdéhùn ọmọ ìlú jẹ´àwọn ohun èlò ti´ó lágbára láti kọ́ ìfẹ´òṣèlú fún àwọn ètò àmúlò ati àwọn èrò ti´ó dára fún àwọn ènìyàn lákòókò ti´ó tún ń ṣe bí ayáṣẹ́ fún àkóyawọ́ nínú ìlànà ìdìbò ati kojú owó àti agbára nínú òṣèlú.

## Ìkádìí

Ìjọba àwa-ara-wa n´ṣẹlẹ̀ ní ojú òpó tii àwọn ọmọ ìlú ati ti àwọn iléeṣẹ́. Gẹ́gẹ́ bí àwọn àṣà tuntun nínú ìmọ`ẹ̀rọ, àwọn ileese aṣojú ati àwọn ilana`ìtọpasẹ`ṣe ìyípadà òṣèlú ní gbogbo àwọn ìpele, bakan náà, ni wọn yóò tún ṣe àlàyé ọ̀nà tí àwọn ará ìlú ati àwọn ìjọba ṣe n´bá ara wọn ṣe. Gẹ́gẹ́ bí àwọn ọ̀nà àsopọ̀ ìbílẹ`ti ìṣàkóso ìjọba tiwantiwa ṣe afihàn àwọn àmì ti´ó wọ́, ìdásílẹ`àti ọgbọ́n ìsẹ̀dá ti dàgbà. Bóyá nípasẹ̀ ìdagbàsókè tàbí lílo àwọn ọ̀nà tuntun ti àlàyé àti ìmọ`ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ tàbí nípasẹ̀ lílo agbára ti àwọn àgbéká àwùjọ láti wakọ̀ ìyípadà òṣèlú, àwọn ará ìlú káàkiri àgbáyé ti n´gbìyànjú láti ṣe àtúnṣe wiwò láàrin àwọn ènìyàn ati òṣèlú. Síbẹ̀síbẹ̀ bí àwọn irú ẹ̀rọ tuntun àti àwọn ọ̀nà ìsiṣẹ´ń yípadà, ìjọba ati iléeṣẹ́ ti kùnà ní ọ̀pọ̀ ìgbà ní ìdáhùn ati agbára wọn láti ní ìbámu sí àwọn ọ̀nà àdéhùn tuntun yìí.

Ìjọba tiwantiwa tó kúnjú òṣùnwọ̀n nílò ikópa ará ìlú lákòókò ati láàrin ètò ìdìbò. Nínú ètò aṣojú, èyí ni a máa n´ṣe nipasẹ`àwọn agbodegba, pẹ̀lú àwọn iléeṣẹ´aṣojú orílẹ`èdè méjèèjì ati ní ìlọsíwájú, àwọn àgbéká òmíràn ati àwọn irú ikani. Fún àwọn ètò ìjọba tiwantiwa láti ṣiṣẹ´ní ìpele ti´ó dara julọ, àwọn ará ìlú ti´ó ń kópa níbi òṣèlú gbọdọ̀ ní ipa nínú gbogbo àwọn ìpele ati àwọn ìpele ètò oṣèlú àti ṣíṣe ìpinnu, pẹ̀lú nínú àwọn iṣẹ́ tó ṣe pàtàkì gẹ́gẹ́ bí i àwọn ìlànà ìdìbò, àláàfìà ati kíkọ òfin lónìí, àwọn ará ìlú n´ṣe iyipada`nipasẹ`dídá sílẹ`ati síṣẹ̀dá àwọn ilana`tuntun ti ikopa ati aṣojú. Dídarí nipasẹ`àwọn ìbéèrè ti ìṣàkóso díẹ`sí i lórí àwọn aṣojú, ìjábọ`sí i, ní ìjọba ati ìkópa tí ó níláárí ju àwọn ìdìbò lọ, àwọn ará ìlú n´tiraka láti ní ipá lórí bí a ṣe ṣẹ̀dá àwọn ètò àmúlò ati ṣe òṣèlú. Ìlànà yìí ti ní iyipadà ní kíkún nípasẹ̀ àwọn ọ̀nà ìmọ`ẹ̀rọ tuntun èyí tí ó fún àwọn ará ìlú díẹ` sí i ní agbára láti sọ àwọn èrò wọn ni ibánisọ̀rọ̀ gbangba tí ó tóbi, tí ó sì ní agbára láti ní ipa nibi ipinnu ètò àmúlò ati àbájáde òṣèlú láti gba ìkópa tí ó pọ̀ sí i àti àwọn ìbéèrè iyipadà ti àwọn ará ìlú, bakan náà àti ìfàṣẹ́yìn tó lòdì tó wà láàrin àwọn ará ìlú ati àwọn olóṣèlú alámọ̀dájú ń ṣẹ̀dá àayè fún àwọn àyípadà ètò ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn orílẹ̀ èdè, pàápàá jùlọ, ní ìpele agbègbè.

# Àwọn ohun èlò síwájú sí I

Change.org[7]:- change.org jẹ́ ojú òpó wẹ̀ẹ̀bù tí ó gba àwọn olùmúlò láàyè láti ṣẹ̀dá àti fọwọ́ sí àwọn ìwé ìpẹ̀jọ́ láti ṣe ìlọsíwájú àwọn oríṣiríṣi okùnfà àwùjọ nípa ṣíṣe ìpolongo ati níní ipa lórí àwọn olùpinnu.

Tracka[8]:- Tracka jẹ´agbègbè ti àwọn ará ìlú ti´ó ń tọpa ìmúṣẹ àwọn iṣẹ´àkànṣe ti ìjọba ní agbègbè wọn láti rí i wí pé wọ́n di mímúṣe.

Shine Your Eye[9]:- Shine your eye jẹ´pẹpẹ ti´ó ṣe ìrànlọ́wọ́´fún àwọn ará ìlú láti wa àwọn aṣojú ti´wọ́n yàn tí ó ń ṣójú wọn ní gbogbo ìpele ìjọba ati so pọ̀ pẹ̀lú wọn.

Advokc[10]:- jẹ´ìpìlẹ`ìmọ`ẹ̀rọ tí a dá sílẹ̀ láti ṣe ìrànwọ´fún àwọn ará ìlú láti kópa, tpa ati mú àwọn tí wọ́n yàn sípò jiyin.

PLAC Bills TRACK[11]:- Bill tracker jẹ´ìwé òfin ti´ó ń tọpa, tí ó fún àwọn iléeṣẹ́ ìpínlẹ` láàyè láti tọpa àwọn ìwé òfin ní gbogbo ilànà ìsòfin. Ó wà ní ìgbàkúgbà láti èyíkéyìí ẹ̀rọ tí ó ní àsopọ̀ pẹ̀lú intanẹ́ẹ̀ti.

Africa Check[12]:- Africa check, jẹ´ọ̀kan lára olómìnira àkọkọ́ tí kò wà fún èrè jíjẹ, tí ó ń ṣàyẹ̀wò otítọ́, pẹ̀lú àtìlẹ́yìn láti ọ̀dọ̀ àwọn ẹgbẹ́ aláàánú àti àwọn olùrànlọ́wọ́ kọ̀ọ̀kan di dídásílẹ̀ ní orílẹ̀ èdè South Africa ní ọdún 2012.

Fact Check Hub[13]:- Fact check Hub jẹ´ìpilẹ̀ṣẹ̀`iléeṣẹ´kárí ayé fún ìwádìí ìròyìn (International Centre for Investigative Reporting (The ICIR) ti´a pín láti kojú àlàyé tí kò tọ´ní àwùjọ. Wọ́n dá a sílẹ̀ ní oṣù Ebibi, ọdún 2020 pẹ̀lú olú iléeṣẹ́ rẹ̀ ní olú ìlú orílẹ`èdè Nàìjíríà ti´ó wà ní Àbújá,, a jẹ́ olómìnira, agbárí aṣàyẹ̀wò otítọ́ láti Áfíríkà.

Fact Check elections[14]:- A jẹ´olómìnira ti´kò rọ̀gbọ̀kú lé ẹgbẹ́ àti pẹpẹ tí kì í ṣe fún èrè. Ohun ti´ó jẹ wá lógún ni láti ṣe ìwádìí ati jẹ́rìí sí àwọn ìròyìn òfegèé láyìíká àwọn ìṣẹlẹ̀ ètò ìdìbò ní orílẹ`èdè Nàìjíríà nípa ṣíṣe ìwádìí, lílo dátà ati àwọn irinṣẹ́ ìmọ`ẹ̀rọ.

Dubawa[15]:- Dubawa jẹ´olómìnira ti ìwọ`Oòrùn Áfíríkà ti´ó wà fún àyẹ̀wò ati iṣẹ́ àkànṣe òtítọ́, tí ó di mímú sí ìmúṣẹ nípasẹ̀ iléeṣẹ́ tí ó ń rí sí àmúgbòòrò iṣẹ´ìròyìn ati ìdàgbàsókè (Centre for Journalism Innovation and Development (CIID) àti ní àtìlẹ́yìn nípasẹ̀ àwọn yàrá ìròyìn ti´ó nípa jùlọ àti àwọn àjọ ìlú ní Ìwọ`Oòrùn Áfíríkà láti ṣe ìrànwọ´láti mú àṣà ti òtítọ́ pọ̀ sí i ní gbangba, ètò gbangba, ati iṣẹ́ oníròyìn. Ó ní wíwà ní orílẹ`èdè Nàìjíríà, Ghana, Sierra Leone, Liberia ati Gambia.

---

7 https://www.change.org
8 https:tracka.ng/#/home
9 https://www.shineyoureye.org/
10 https://www.advockc.org/
11 https://placbillstrack.org
12 https://africacheck.org/
13 https://factcheckhub.com/
14 https://factcheckelections.org/
15 https://dubawa.org/

BRAIN BUILDERS
YOUTH DEVELOPMENT
INITIATIVE

# Irinṣẹ́ Ìjábọ̀ fún ará Ìlú

Sponsored by: LEAP AFRICA, NIGERIA YOUTH FUTURES FUND